25

# ẸKÚN JEREMIAH

**(B.C. 588)**

ORI 1.

**A kó Jerusalemu lọ si ìgbèkùn.**

BAWO ni ilu ṣe jókòó ni oun nikan ṣoṣo, ti o ti kun fun eniyan ri! ó wà bi opó! oun ti i ṣe ẹni-nla laarin awọn orilẹ-ede! ọmọ-alade obinrin laarin igberiko, oun si wa di ẹni ìmúsìn. (Isa 3:26; 54:4; Esra 4:20; Jer 40:9.)

2. Oun sọkun kíkorò gidigidi ni òru, omijé rẹ̀ si wa ni ẹrẹkẹ rẹ̀: laarin gbogbo awọn olufẹ rẹ̀, kò ni ẹnikẹni lati tù ú ninu: gbogbo awọn ọrẹ rẹ̀ ti fi arekérekè ba a lò, wọn di ọ̀tá rẹ̀. (Psm 6:6; Jer 2:25; 4:30.)

3. Juda lọ si àjò nitori ipọnju ati ìsìn-ẹrú nla: o ngbe nisinsinyií laarin awọn orilẹ-èdè, sugbọn oun kò rí isinmi: gbogbo awọn ti nlepa rẹ̀ ba a ni ibi híhá. (Jer 13:19; Deut 28:64,65; 2 A.Ọba 25:4,5.)

4. Awọn ọ̀nà Sioni nṣọ̀fọ̀, nitori ẹnikan kò wá sí àjọ tí a yàn: gbogbo ẹnu-bode rẹ̀ dahoro: awọn alufa rẹ̀ nkédùn, awọn wundia rẹ̀ nkaanu, oun pẹlu si njẹrora kíkorò ni ọkàn rẹ̀. (Jer 9:11; 10:22; Joel 1:8–13.)

5. Awọn aninilara rẹ̀ di olori rẹ̀, awọn ọ̀tá rẹ ṣe rere: nitori OLUWA ti pọn ọn loju nitori ọpọlọpọ irekọja rẹ̀; awọn ọmọ wẹrẹ rẹ̀ lọ si ìgbèkùn niwaju awọn aninilara. (Deut 28:43,44; Jer 30:14,15; 39:9; 52:28.)

6. Gbogbo ẹwà ọmọbinrin Sioni si ti lọ kuro lọdọ rẹ̀: awọn ijoye rẹ̀ dabi agbọnrin ti kò rí pápá oko tútù jẹ, wọn si lọ laini agbara niwaju awọn ti nlepa wọn. (Jer 13:18; 2 A.Ọba 25:4,5.)

7. Ni ọjọ ipọnju rẹ̀ ati inilara rẹ̀ ni Jerusalemu ranti gbogbo ohun daradara ti o ti ní ní ọjọ igbaani, nigba ti awọn eniyan rẹ̀ ṣubu si ọwọ́ ọ̀tá, ẹnikan kò sì ràn án lọwọ: awọn aninilara ri i, wọn si fi iparun rẹ̀ ṣẹ̀sín. (Psm 42:4; Isa 5:1–4; Jer 37:7; E.Jer. 4:17; Jer 48:27.)

8. Jerusalẹmu ti dá ẹ̀ṣẹ̀ gidigidi, nitori naa ni o ṣe di ẹni-irira: gbogbo awọn ti nbu ọla fun un kẹgan rẹ̀, nitori pe wọn ri ìhòhò rẹ̀; bẹẹ ni oun tìkárarè kẹ́dùn ó sì yi ojú sẹ́hìn. (1 A.Ọba 8:46; ẹsẹ 5,17,20; Jer 13:22,26; ẹsẹ 4 11:21,22.)

9. Eeri rẹ̀ wà ni iṣẹti aṣọ rẹ̀; oun kò sì ranti iparun rẹ̀ ikẹhin; nitori naa ni iṣubu rẹ̀ ṣe bani lẹ́rù: kò ní olutunu, "Oluwa, wo ipọnju mi, nitori ọ̀tá ti bori! (Esk 24:13; Deut 32:29; Isa 47:7; Jer 13:17,18; 16:7.)

10. Aninilara ti na ọwọ́ rẹ̀ jade sori gbogbo ohun daradara rẹ̀: nitori oun ti ri pe awọn orilẹ-èdè wọ ibi-mimọ rẹ, eyi ti iwọ paṣẹ pe, wọn kò tilẹ̀ gbọdọ wọ inu ijọ tirẹ. (Isa 64:10,11; Jer 51:51; Deut 23:3.)

11. Gbògbo awọn eniyan rẹ kerora bi wọn ti nwá ounjẹ; wọn fi ohun-ìní wọn daradara fun ounjẹ ki wọn lè ni agbara. "Wo o Oluwa, ki o si ro! nitori emi di ẹni-ẹ̀gàn." (Jer 38:9; 52:6; 1 Sam 30:12.)

**Ẹṣẹ Jerusalẹmu di mímọ̀.**

12. "Ko ha jẹ nkankan fun yin bi, gbogbo ẹyin ti nkọja lọ? Wo o, ki ẹ si ri bi ibanujẹ kan ba wa ti o dabi ibanujẹ mi, ti a ṣe si mi! eyi ti OLUWA fi pọn mi loju ni ọjọ ibinu gbigbona rẹ̀." (Jer 18:16; 48:27; ẹsẹ 18; Jer 30:23,24; 4:8.)

13. "Lati òkè ni a ti ran iná sínú egungun mi, o si ràn ninu rẹ̀: Oun ti na àwọn fun ẹsẹ̀ mi, o ti yi mi pada sẹhin; O ti mu mi dahoro ati òtòṣì, mo si rẹ̀wẹ̀sì." (Job 30:30; Hab 3:16; Job 19:6; Jer 44:6.)

14. "Okùn àjàgà irekọja mi ni a dimu ni ọwọ́ rẹ̀; a so wọn pọ: wọn yi

ọrùn mi ká, o ti mu ki agbara mi kùnà; Oluwa ti fi mi le ọwọ́ awọn ẹni ti emi ko le kò loju. (Deut 28:48; Isa 47:6; Jer 28:13,14; 32:3,5; Esk 25:4,7.)

15. "Oluwa ti tẹ gbogbo awọn akọni mi mọlẹ labẹ ẹsẹ ni aarin mi: Oun ti pe apejọ sori mi lati tẹ awọn ọdọmọkunrin mi rẹ: Oluwa ti tẹ ifunti fun wundia, ọmọbinrin Juda." (Isa 41:2; Jer 13:24; 18:21; Isa 28:18; Mika 7:10; Ifh 14:19.)

16. "Emi nsọkun nitori nkan wọnyií; oju mi! oju mi ṣan omi silẹ, nitori pe olutunu ati ẹni ti ìbá mu ọkan mi sọji jinna si mi: awọn ọmọ mi run, nitori pe ọ̀tá bori." (Jer 13:17; 14:17; E.Jer. 2:18; ẹsẹ 2,9.)

17. Sioni na ọwọ́ rẹ̀ jade, kò sì sí ẹnikan lati tu u ninu: Oluwa ti paṣẹ ni ti Jakobu pe, ki awọn aladugbo rẹ̀ o di ọta rẹ̀: Jerusalemu dabi ohun ẹlẹ́gbin laarin wọn. (Jer 4:31; 2 A.Ọba 24: 2–4; ẹsẹ 8.)

18. "Oluwa ṣe olododo; nitori ti emi ti ṣọtẹ si aṣẹ ẹnu rẹ̀: gbọ, (emi bẹ yin,) gbogbo orilẹ-ede, ẹ si wo ikaanu mi; awọn wundia mi ati awọn ọdọmọkunrin mi ti lọ si ìgbèkùn. (Jer 12:1; 1 Sam 12:14; ẹsẹ 12; Deut 28:32,41.)

19. "Emi pe awọn olufẹ mi, awọn wọnyií tan mi jẹ, awọn alufa mi, ati alagba mi ni a parun ni ìlú, nigba ti wọn nwa ounjẹ wọn lati mu ẹ̀mí wọn wà laaye. (Jer 30:14; 14:15; E.Jer. 2:20.)

20. "Wo o, Oluwa: nitori ti emi wà ninu ipọnju: inu mi nhó; ọkàn mi yipada ninu mi: nitori ti emi ti ṣọ̀tẹ̀ gidigidi: lode, ida sọni di alailọmọ, ni ilé, o dabi ikú! (Isa 16:11; Jer 4:19; E.Jer. 2:11; Deut 32:29; Esk 7:15.)

21. Wọn gbọ bi emi ti nkẹdun to: sibẹ kò si olùtùnú fun mi: gbogbo awọn ọta mi gbọ́ iyọnu mi; inu wọn dun nitori iwọ ti ṣe e: iwọ o mu ọjọ naa wa ti iwọ ti da, wọn o si ri gẹgẹ bi emi. (E.Jer. 2:15; Isa 14,5,6; Jer 30:16.)

22. "Jẹ ki gbogbo iwa-buburu wọn wa si iwaju rẹ; si ṣe si wọn gẹgẹ bi iwọ ti ṣe si nitori gbogbo irekọja mi: nitori ikẹdun mi pọ, ọkan mi si rẹwẹsi." (Neh 4:4,5; Psm 137:7,8.)

ORI 2.

**Idajọ Oluwa.**

BAWO ni Oluwa ti fi ikuukuu awọsanma bo ọmọbinrin Sioni ni ibinu rẹ̀! ti o sọ ẹwà Israẹli kalẹ lati òkè ọrun wa si ilẹ, ti ko si ranti apoti-itisẹ rẹ ni ọjọ́ ibinu rẹ̀! (E.Jer. 3:43,44; Esk 28: 14–16; Isa 64:11; Psm 99:5; 132: 7.)

2. Oluwa ti gbe gbogbo ibugbe Jakobu mì, ko si da a si: o ti wó ìlú odi ọmọbinrin Juda lulẹ, ninu irunu rẹ̀ o ti wo ijọba naa ati awọn ijoye rẹ lulẹ, o sọ wọn di ibajẹ, gbogbo wọn si di alaimọ. (Psm 21:9; E.Jer. 3:43; Mika 5:11,14; Isa 25:12; Psm 89: 39.)

3. O ti ge gbogbo ìwo Israẹli kuro ninu ibinu gbigbona rẹ̀: o ti fa ọwọ́ ọtun rẹ sẹ́hìn niwaju ọ̀tá, o si jo gẹgẹ bi ọwọ́ iná ninu Jakọbu ti o jẹrun yikakiri. (Psm 75:5,10; 74:11; Jer 21:4,5; 21:14.)

4. O ti fa ọrun rẹ̀ gẹgẹ bi ọ̀tá: o duro, o mura ọwọ́ ọtun rẹ gẹgẹ bi aninilara, o si pa gbogbo igberaga oju wa run ninu agọ ọmọbinrin Sioni, o da irunu rẹ jade bi iná. (E.Jer. 3:12,13; Esk 24:25; Isa 42:25; Jer 7:20.)

5. Oluwa jẹ gẹgẹ bi ọtá: o ti pa Israẹli run, o ti pa gbogbo aafin rẹ̀ run: o ti pa ìlú olodi rẹ̀ run, o si sọ ìkérora ati ibanujẹ di pupọ fún ọmọbinrin Juda. (Jer 30:13; 6:26; 9:17–29.)

6. O si ti wó àgọ́ rẹ lulẹ̀, gẹgẹ bi agbala: o ti pa ibi apejọ rẹ run: Oluwa ti mu ki a gbagbe ajọ-mimọ ati ọjọ isinmi ni Sioni, ninu irunu ibinu rẹ̀, o ti fi ègàn kọ ọba ati alufa silẹ. (Jer 7:14; 52:13; E.Jer 1:4; Sef 3:18; E.Jer 4:16,20; 5:12.)

7. Oluwa ti ṣá pẹpẹ rẹ tì, o ti korira ibi-mímọ́ rẹ, o ti fi ogiri aafin rẹ le ọwọ́ ọta; wọn ti pa ariwo ninu ile OLUWA,

gẹgẹ bi ni ọjọ àjọ mimọ. (Isa 64:11; Esk 7:20–22; Jer 33:4,5; Psm 74:4.)

8. Oluwa ti ro lati Pa odi ọmọbinrin Sioni run: o ti na okùn ìwọ̀n jade, oun ko ti fa ọwọ́ rẹ sẹhin kuro ninu ipanirun: bẹẹ ni o ṣe ki ile-iṣọ rẹ ati odi rẹ o ṣọ̀fọ̀; wọn jumọ di rírẹ̀ silẹ. (Jer 5:10; 2 A.Ọba 21:13; Isa 34:11; 3:26; Jer 14:2.)

9. Awọn ẹnu-bode rẹ̀ ti rì si ilẹ; o ti parun o si ṣẹ igi-idabu rẹ̀; ọba rẹ̀ ati awọn ijoye rẹ̀ wa laarin awọn orilẹede: ofin kò si mọ; awọn woli rẹ̀ pẹlu ko ri ìran lati ọdọ Oluwa. (Neh 1:3; Jer 51:30;Deut 28:36; 2 A.Ọba 24:15; 2 Kro 15:3; Jer 14:14; 23:16; Esk 7:26.)

10. Awọn àgbàgbà ọmọbinrin Sioni jokòó ni ilẹ, wọn dakẹ: wọn ti ku ekuru sori wọn; wọn ti fi aṣọ-ọ̀fọ̀ di ara wọn: awọn wundia Jerusalẹmu so orí wọn kọ si ilẹ. (Job 2:13; Isa 3:26; Isa 3:26; Amos 8:3; Job 2:12; Esk 27:30,31; Isa 15:3; E.Jer. 1:4.)

11. Oju mi gbẹ tán fun omije, inu mi nho, a da ẹ̀dọ̀ mi sori ilẹ, nitori iparun ọmọbinrin awọn eniyan mi; nitori pe awọn ọmọ wẹẹrẹ ati awọn ọmọ-ọmú nkulọ ni ìta ilu naa. (Psm 6:7; E.Jer. 3:48; 1:20; Job 16:13; Psm 22:14; E.Jer. 4:4.)

12. Wọn nsọ fun ìyá wọn pe, "Nibo ni ọka ati ọti-waini gbe wa?" Nigba ti wọn daku gẹgẹ bi awọn ti a ṣálọ́gbẹ́ ni ìta ilu naa, nigba ti ẹmi wọn dà jade ni àyà ìyá wọn. (Jer 5:17; E.Jer. 4:4; Job 30:16.)

13. Kinni ohun ti emi o fi ṣe iranti rẹ? Kinni ohun ti ale fi we ọ iwọ ọmọbinrin Jerusalẹmu? Kinni emi o sì fi ó wé, lati le tẹ ọ lọrun, iwọ wundia ọmọbinrin Sioni? Nitori pe ọgbẹ rẹ tobi gẹgẹ bi òkun; tani ó lè wò ọ sàn? (E.Jer 1:12; Isa 37:22; Jer 14:17; 8:22; 30:12-15.)

**Awọn woli èké Sioni.**

14. Awọn woli rẹ ti riran ohun asán ati wèrè fun ọ: wọn kò sì fi aiṣedeede rẹ han ọ, lati yi igbekun rẹ pada kuro; ṣugbọn wọn ri ìran iṣẹ́-wíwò èké fun ọ ati ohun ti nmuniṣìnà. (Jer 2:8; 29:8,9; Isa 58:1; Jer 23:36; Esk 22: 25,28.)

15. Gbogbo awọn ti nkọja patẹwọ le ọ; wọn pòṣé, wọn si nmi orí si ọmọbinrin Jerusalẹmu, pe, "Ilu naa ha ni èyí, ti a npe ni: Pipé-ẹwà, Ayọ gbogbo ilẹ ayé!" (Jer 19:8; Sef 2:15; Isa 37:22; Psm 48:2; 50:2.)

16. Gbogbo awọn ọta rẹ ya ẹnu wọn si ọ; wọn nṣe ṣiọ! wọn si npa ehín keke, wọn wi pe; "Awa ti gbé e mì; dajudaju èyí ni ọjọ naa ti awa ti nwọ̀nà fun; ọwọ́ ti tẹ̀ é, awa ti ri i!" (Psm 22:13; E.Jer. 3:46; Psm 37:12; 56:2; Obad 12–15.)

17. Oluwa ti ṣe eyi ti o ti rò; o ti mu ọ̀rọ̀ rẹ̀ ṣẹ ti o ti paṣẹ ni ọjọ igbaani: o ti bì ṣubu, laisi aanu: o si ti mu ọ̀tá yọ̀ lori rẹ, o ti gbe ìwo awọn aninilara rẹ sókè. (Deut 28:15; Jer 18:11; ẹsẹ 1,2; Psm 35:24,26; E.Jer. 1:5.)

18. Ọkàn wọn kigbe si Oluwa, iwọ ògiri ọmọbinrin Sioni, jẹ́ ki omijé ṣàn silẹ̀ gẹgẹ bi odò lọ́sàn ati lóru; máṣe fún ara rẹ ni isinmi; máṣe jẹ́ ki ẹyin ojú rẹ gbé jẹ́. (Hos 7:14; Jer 9:11; E.Jer 1:2, 16.)

19. Dide, kigbe soke ni òru ni ibẹrẹ akoko ìṣọ́: tú ọkàn rẹ jade gẹgẹ bi omi niwaju Oluwa: gbe ọwọ́ rẹ soke si i fun ẹmi awọn ọmọ wẹwẹ rẹ, ti nkulọ fun ebi ni gbogbo orí-ìta. (Psm 42:3; Isa 26:9; Psm 62:8; Isa 51:20.)

20. Wo o, Oluwa, ki o rii, fun ẹni iwọ ti ṣe eyi? Awọn obinrin ha lè maa jẹ eso-inu wọn, awọn ọmọ-ọwọ ti wọn ńpọ̀n? A ha le maa pa alufa ati woli ni ibi mimọ Oluwa? (Jer 19:9; 14:15; E.Jer. 4:13,16.)

21. Ewe ati arúgbó dubulẹ ni igboro: awọn wundia mi ati awọn ọdọmọkunrin mi ṣubu nipa idà: iwọ ti pa ni ọjọ ibinu rẹ; iwọ ti pa wọn laì sí aanú. (2 Kro 36:17; Jer 6:11; Psm 78:62,63; Jer 13:14; Sek 11:6.)

22. Iwọ ti ke pe ẹ̀rù mi níhà gbogbo

gẹgẹ bi ni ọjọ àsè, tobẹẹ ti ẹnikan ko sálà tabi ki o kù ni ọjọ ibinu Oluwa: awọn ti mo ti pọ̀n ti mo si tọ́, ni ọ̀tá mi ti run. (Psm 31:13; Jer 6:25; Hos 9: 12,13.)

ORI 3.

**Pohunrere-ẹkun lori Sioni.**

EMI ni ọkunrin naa ti o ti ri wahala nipa ọpa ibinu rẹ. (Job 19:21; Jer 15:17,18.)
2. Ó ti fà mi, o sì mu mi wá sinu òkùnkùn, ki si i ṣe sinu imọlẹ. (Isa 59:9; Jer 4:23.)
3. Lootọ o yi ọwọ rẹ pada si mi siwaju ati siwaju ni ọjọ gbogbo. (Isa 5:25.)
4. O ti sọ ẹran-ara mi ati awọ mi di ogbó, o ti fọ́ egungun mi. (Job 16:8; Psm 51:8; Isa 38:13; Jer 50:17.)
5. O ti mọdi tì mí, o fi ìkorò ati ipọnju yìí ká. (Job 19:8; Jer 23:15.)
6. O ti fi mi si ibi òkùnkùn, bi awọn ti o ti kú pẹ́. (Psm 88:5,6.)
7. O ti ṣọgba yí mi ká, ti emi kò lè jade; o ti gbe ẹ̀wọ̀n le mi. (Job 3:23; Jer 40:4.)
8. Bi emi ti kigbe pẹlu, ti emi si npariwo, ó sé adura mi mọ́. (Job 30:20; Psm 22:2.)
9. O ti fi okuta gbígbẹ́ ṣọgbà yi ọ̀nà mi ká, o ti yi ipa ọ̀nà mi po. (Hos 2:6; Isa 63:17.)
10. Oun jẹ bi ẹranko beari ti o ba dè mi, bi kinniun ni ibi ìkọ̀kọ̀. (Job 10:16; Isa 38:13.)
11. O ti mu mi ṣina ni ọ̀nà mi, o si fà mi ya pẹ́rẹpẹ̀rẹ: o ti sọ mi di ahoro. (Hos 6:1.)
12. O ti fa ọrun rẹ̀, o sì fi mi ṣe àmì fun ọfa rẹ̀. (Psm 7:12,13; Job 7:20.)
13. O ti mu ki ọfà apó rẹ̀ wọ inu-ẹ̀dọ̀ mi lọ. (Job 6:4.)
14. Emi jẹ ẹni ẹ̀sín fun gbogbo eniyan mi; orin wọn ni gbogbo ọjọ́. (Jer 20:7; Job 30:9.)
15. O ti fi ikoro mu mi yo, o ti mú mi mu omi wahala. (Jer 9:15.)
16. O ti fi ehín mi fọ okuta wẹwẹ, o tẹ mi mọlẹ ninu eérú. (Owe 20:17; Jer 6:26.)
17. Iwọ si ti mu ọkan mi jinna réré si alaafia; emi ti gbàgbé ohun ti ayọ̀ jẹ́ (Jer 12:12.)
18. Emi si wi pe, "Agbara mi ati ireti mi ṣègbé kuro lọdọ Oluwa." (Psm 31:22.)
19. Ranti wahala mi ati inilara mi, ani ikorò ati òroorò. (Jer 9:15.)
20. Lootọ, nigba ti ọkan mi nṣe iranti wọn, o si tẹriba ninu mi. (Psm 42:5,6,11.)

**Ìpè fun aanu Ọlọrun.**

21. Eyi ni emi o rò ni ọkàn mi, nitori naa emi o maa reti. (Psm 130:7.)
22. Aanu Oluwa ni, ti awa kò parun tán, nitori irọ́nú-aanu rẹ̀ kò ní òpin. (Mal 3:6.)
23. Ọ̀tun ni ní òròwurọ; titobi ni otitọ rẹ. (Sef 3:5.)
24. "Oluwa ni ìpín mi bẹẹ ni ọkan mi wi;" nitori naa ni emi ṣe ni ireti ninu rẹ̀. (Psm 16:5; 33:18.)
25. Oluwa ṣe rere fun gbogbo ẹni ti o duro dè é, fun ọkàn ti o ṣàférí rẹ̀. (Isa 25:9; 30:18; 26:9.)
26. O dara bi a bá lè maa retí ni idakẹjẹ fun igbala Oluwa. (Psm 37:7; 40:1; Isa 30:15.)
27. O dara fun ọkunrin, ki o gbe ajaga ni ìgbà-èwe rẹ̀. (Psm 94:12.)
28. Ki o jókòó oun nikan, ki o si dakẹ, nitori Ọlọrun ti gbe àjàgà naa le orí rẹ̀. (Jer 15:17.)
29. Ki o fi ẹnu rẹ̀ sinu eekuru; pe boya ireti lè wà: (Job 16:15; Jer 31:17.)
30. Ki o fi ẹrẹkẹ fun ẹni ti o lu u; ki o kun fun ègàn patapata. (Isa 50:6; Matt 5:39.)
31. Nitori ti Oluwa ki yoo ṣá ni tì laelae; (Psm 94:14.)
32. Bi o tilẹ mu ibanujẹ wá, sibẹ oun o ni ìrọ̀nú gẹgẹ bi ọpọlọpọ ifẹ ati aanu rẹ̀. (Psm 78:38; Hos 11:8.)
33. Nitori oun ki i fẹ pọn-ni-loju lati ọkàn rẹ̀ wá, bẹẹ ni ki i ba ọmọ eniyan ninu jẹ́. (Esk 33:11; Heb 12:10.)

34. Lati tẹ gbogbo ará-tubu ilẹ-ayé mọlẹ ni abẹ ẹsẹ̀.
35. Lati yi ẹ̀tọ́ eniyan sápákan niwaju Ọga-ogo julọ. (Psm 140:12.)
36. Lati yi ọ̀ràn idajọ eniyan padà, Oluwa kò fẹ́ rí i? (Hab 1:13.)
37. Tani ẹni ti nwi, ti i si nṣe, nigba ti Oluwa kò paṣẹ rẹ̀. (Psm 33:9.)
38. Ibi ati rere kò ha njade lati ẹnu Ọga-ogo-julọ wa? (Job 2:10; Isa 45:7; Jer 32:42.)
39. Eeṣe ti eniyan alaaye nkùn, eniyan, ti nkùn sí ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀. (Mika 7:9; Heb 12:5,6.)

**Ìpè si Israẹli lati yipada si Oluwa.**

40. Jẹ ki a wadi, ki a si dan ọ̀nà wa wò, ki a si tun yipada si Oluwa. (Psm 119:59; 2 Kor 13:5.)
41. Jẹ ki a gbe ọkan ati ọwọ́ wa soke si Ọlọrun ni ọ̀run. (Psm 25:1; 28:2.)
42. "Awa ti dẹ́ṣẹ̀, a si ti ṣọ̀tẹ̀: iwọ kò si dariji. (Dan 9:5; Jer 5:7,9.)
43. Iwọ ti fi ibinu bora, o si lepa wa; iwọ ti pa, o kò sì ṣe aanu. (E. Jer 2:21; Psm 83:15.)
44. Iwọ ti fi ikuukuu awọsánmà bo ara rẹ ki adura kan ma baa lè kọjá (Psm 97:2; ẹsẹ 8.)
45. Iwọ ti ṣe wá bi ìdàrọ́ ati ohun alainilaari ni aarin awọn orilẹ-èdè. (1 Kor 4:13.)
46. "Gbogbo awọn ọ̀tá wa ti ya ẹnu wọn sí wa. (E.Jer. 2:16.)
47. Ẹrù ati ọ̀fìn wá sori wa, idahoro ati iparun. (Isa 24:17; Jer 48:43; Isa 51:19.)
48. Oju mi nṣan fun odò omije, nitori iparun ọmọbinrin awọn eniyan mi. (E.Jer. 1:16; 2:11,18.)
49. "Oju mi yoo da omije silẹ̀, láìdúró, laiṣe isinmi. (Psm 77:2.)
50. Títí Oluwa lati ọ̀run yoo boju wo ilẹ̀ ti o sì ri i. (Isa 63:15.)
51. Oju mi npọ́n ọkàn mi loju, nitori gbogbo awọn ọmọbinrin ilu mi.
52. "Awọn ọ̀tá mi dẹkùn fun mi gidigidi, gẹgẹ bi fun ẹyẹ laini ìdí. (Psm 35:7.)
53. Wọn tì mí sí kòtò láàyè, wọn si kó okuta le ori mi. (Jer 37:16.)
54. Wọn mú omi ṣan lori mi; emi wi pe, Mo gbe! (Psm 69:2; Isa 38:10.)

**Ìpè fun ẹ̀san lori awọn ọ̀tá Israẹli.**

55. "Emi ke pe orukọ rẹ, Oluwa, lati iho jínjìn wa. (Jona 2:2.)
56. Iwọ ti gbọ ohun mi: maṣe di etí rẹ si igbe mi fun iranlọwọ. (Psm 116:1,2.)
57. Iwọ sunmọ tòsí ni ọjọ ti emi kigbe pe ọ: iwọ wi pe: Má bẹru! (Psm 145:18; Isa 41:10,14.)
58. "Oluwa, iwọ ti gba ìjà mi jà; iwọ ti rà mi padà. (Jer 51:36; Psm 71:23.)
59. Oluwa, iwọ ti ri aṣiṣe mi, ṣe idajọ ọ̀ràn mi! (Jer 18:19,20; Psm 35:23.)
60. Iwọ ti ri gbogbo ìgbẹ̀san wọn, gbogbo èrò buburu wọn si mi. (Jer 11:19,20; 18:18.)
61. "Iwọ ti gbọ ẹ̀gàn wọn, Oluwa, ati gbogbo èrò buburu wọn si mi. (E.Jer. 5:1.)
62. Ètè ati èrò awọn akọluni dide si mi ni gbogbo ọjọ (Esk 36:3.)
63. Kiyesi ìjokòó wọn ati idide wọn; emi ni orin-ẹ̀sín wọn. (Psm 139:2.)
64. "San ẹsan fun wọn, Oluwa, gẹgẹ bi iṣẹ́ ọwọ́ wọn! (Psm 28:4.)
65. Fun wọn ni ifọju ọkàn, ègún rẹ̀ yoo wa lori wọn! (Isa 6:10.)
66. Fi ibinu lepa wọn, ki o si pa wọn run kuro labẹ ọrun Oluwa! (Psm 8:3.)

## ORI 4.

**Abayọri igbogun tì naa.**

BAWO ni wura ṣe di bàìbàì! bawo ni wura didara julọ ṣe yipada! okuta ibi-mimọ ni a tuka ni gbogbo orí ìta. (Esk 7:19–22; Jer 52:13,14.)
2. Awọn iyebiye ọmọ Sioni, ti o niye lori bi wura didara, bawo ni a ṣe ka wọn si bi ìkòkò amọ̀, iṣẹ ọwọ alámọ̀! (Isa 51:18; 30:14; Jer 19:11.)
3. Ani awọn akata nfa ọmú jade, wọn nfi ọmú fun awọn ọmọ wọn: ṣugbọn ọmọbinrin awọn eniyan mi ti

di ìkà, gẹgẹ bi abo ògòngò ni aginju.
(Isa 34:13; 49:15; Job 39:14,16.)
4. Ahọ́n ọmọ-ọmu lẹ̀ mọ́ òkè ẹnu rẹ̀
fún oungbẹ: awọn ọmọ kekere nbèèrè
ounjẹ, ẹnikan kò sì fi i fún wọn. (Jer
14:3; E.Jer. 2:12.)
5. Awọn ti o ti njẹ ohun didundidun
nku lọ ni ìta: awọn ti a ti tọ́ ninu
aṣọ-òdòdó, sun lori òkìtì-eérú. (Jer
6:2; Amos 6:3–7; Psm 113:7.)
6. Nitori aiṣedeede ọmọbinrin eni-
yan mi tobi ju ẹ̀ṣẹ̀ Sodomu lọ, ti a bì
ṣubú ni iṣẹju-kan laisi gbé ọwọ́ le wọn.
(Esk 16:48; Gen 19:23; Jer 20:16.)
7. Awọn ọmọ-alade rẹ mọ́ ju
ẹ̀gbọ̀n-òwú, wọn funfun ju wàrà; irisi
wọn pọn ju iyùn, apẹrẹ wọn dabi
okuta Safire: (Psm 51:7.)
8. Oju wọn dudu ju èédú nisinsinyìí;
a ko mọ wọn ni ita: àwọ̀ wọn lẹ̀ mọ́
egungun wọn; o di gbigbẹ gẹgẹ bi igi.
(Job 30:30; E.Jer. 5:10; Psm 102:5.)
9. Awọn ti a fi idà pa sàn ju awọn ti
a fi ebi pa, ti ndaku lọ, ti ọwọ iyà ti bà
nitori àìsí èso-oko. (Jer 15:2; Esk
24:23.)
10. Ọwọ awọn obinrin alaanu ni o
se ọmọ awọn tikarawọn: awọn ọmọ
wọnyìí ni ohun-jijẹ fun wọn ni ìgbà
wahala ọmọbinrin awọn eniyan mi.
(E.Jer. 2:20; 2 A.Ọba 6:29; Deut
28:57.)
11. Oluwa ti ṣe aṣepe irunu rẹ̀; o ti
da ibinu gbogbona rẹ̀ jade, o ti dá iná
ni Sioni, ti o si ti jó ipilẹ rẹ̀ run. (Jer
7:20; ẹsẹ 22; Deut 32:22; Jer 21:14.)
12. Awọn ọba ayé, ati gbogbo
olugbe ilẹ-ayé, ko gbagbọ pe aninilara
ati ọ̀tá lè wọ ẹnu-bode Jerusalẹmu.
(1 A.Ọba 9:8; Jer 21:13.)

**Iṣẹ ibi awọn woli èké.**

13. Nitori ẹ̀ṣẹ̀ awọn woli rẹ̀, ati aiṣe-
déédé awọn alufa rẹ̀, ti wọn ti ta ẹ̀jẹ̀
awọn olódodo silẹ ni aarin rẹ̀. (Jer
5:31; 6:31; Eks 22:26; Mika 3:11,12;
Matt 23:31.)
14. Wọn ti rìn kiri bi afọju ni ìta,
wọn di alàìmọ́ fun ẹ̀jẹ̀, tobẹẹ ti eniyan
kò lè fi ọwọ kan aṣọ wọn. (Isa 56:10;
59:9,10; Jer 19:4; 2:34.)
15. Awọn eniyan nkigbe si wọn pe,
"Ẹ lọ kuro alàìmọ́! ẹ lọ! ẹ lọ! ẹ máṣe fi
ọwọ kàn án! nigba ti wọn salọ, wọn sì
rìn kiri pẹlu: awọn eniyan nwi laarin
awọn orilẹ-èdè pe, wọn ki yoo ṣàtìpò
nibẹ mọ." (Lef 13:45; Jer 49:5.)
16. Ibinu Oluwa ti tú wọn ká: oun ki
o sì kà wọ́n sí mọ́: wọn kò buyìn fun
awọn alufa, wọn kò ṣaanu fun awọn
àgbàagbà. (E.Jer. 5:12.)

**Ko si oluranlọwọ.**

17. Bi o ṣe tiwa ni, oju wa nsú lọ ni
wíwọ̀nà ṣá fun iranlọwọ asán: lori ile-
iṣọ wa, awa wọ̀nà fun orilẹ-èdè, ti kò
lè ran ni lọ́wọ́. (2 A.Ọba 24:7; Isa
20:5; Jer 37:7; Esk 29:16.)
18. Wọn dẹkùn si ipa ọ̀nà wa, ti awa
kò lè rin ìta wa: opin wa sunmọ tòsí,
ọjọ wa pé; nitori opin wa dé. (2 A.Ọba
25:4; Esk 7:2,3; Amos 8:2.)
19. Awọn ti nlepa wa yara ju ìdì
ọrun lọ: wọn nlepa wa lori awọn òkè,
wọn ba dè wa ni aginju. (Deut 28:49;
Jer 4:13; Hab 1:8.)
20. È émi iho imu wa, ani ẹni-òróró
Oluwa, ni a mu ninu ọ̀fin wọn, ni ti ẹni
ti awa wi pe, "Labẹ ojiji rẹ̀ ni awa o
maa gbé laarin awọn orilẹ-èdè." (2
Sam 1:14; 19:21; Esk 12:13; 19:4,8.)

**Elẹṣẹ yoo jiya ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀.**

21. Yọ̀, ki inu rẹ sì dùn, iwọ
ọmọbinrin Edomu, ti ngbe inu ilẹ Usi;
sibẹ ago naa yoo kọja sọdọ rẹ pẹlu:
iwọ o si mu ọtí yó, iwọ o si tu ara rẹ si
ìhòhò. (Isa 34:7; Amos 1:11,12; Obad
16.)
22. A mu aiṣedeede rẹ kuro, iwọ
ọmọbinrin Sioni: oun ki o si tun mu ọ
lọ si ìgbèkùn mọ: Oun o bẹ aiṣedeede
rẹ wò, iwọ ọmọbinrin Edomu; yoo si
fi ẹṣẹ rẹ̀ han. (Isa 40:2; Mal 1:3,4.)

ORI 5.

**Ẹṣẹ wọn ati ìwà ibi wọn di mímọ̀.**

RANTI, Oluwa, ohun ti o de sori
wa; rò sì wo ẹ̀gàn wa! (Psm
89:50; 44:13–16.)

2. A fi ogún wa lé awọn àlejò lọwọ, ilẹ wa fun awọn àjèjì. (Psm 79:1; Sef 1:13.)
3. Awa jẹ alaini òbí, baba kò sí, awọn ìyá wa dabi opó. (Jer 15:8; 18:21.)
4. Awa tun nsan ówó ki ato mu omi wa; igi wa ni wọn si tun ntà fun wa. (Isa 3:1.)
5. Awọn ti nlepa wa sunmọ ọrùn wa: àárẹ mu wa, awa kò sì ni isinmi. (Jer 28:14; Neh 9:36,37.)
6. Awa ti fi owó fun awọn ara Egipti, ati fun ara Assiria, lati fi ounjẹ tẹ́ wa lọrun. (Jer 2:36; Hos 5:13; 7:11; 9:3.)
7. Awọn baba wa ti ṣẹ, wọn kò sì sí; awa si nru aiṣedeede wọn. (Neh 5:15; Sek 11:6.)
8. Awọn ẹrú ti jọba lori wa: ẹnikan kò sì gbà wá kuro ni ọwọ́ wọn.
9. Ninu ewu ẹmi wa ni awa nlọ mu ounjẹ wá, nitori idà ni aginju.
10. Awọ wa pọn gẹgẹ bi ààrò nitori gbigbona iyàn naa. (E.Jer 4:8.)
11. Wọn tẹ́ awọn obinrin l'ogo ni Sioni, awọn wundia ni ilu Juda. (Isa 13:16; Sek 14:2.)
12. A so awọn ìjòyè rọ̀ nipa ọwọ wọn: a kò buyin fun oju awọn agbagba. (E.Jer. 4:16.)
13. Awọn ọdọmọkunrin ru ọlọ, àárẹ mu awọn ọmọdé labẹ ẹru-igi. (Jer 7:18.)
14. Awọn agbaagba dáṣẹ̀ kuro ni ẹnu-bodè, awọn ọdọmọkunrin kuro ninu orin wọn. (E.Jer. 4:8; Jer 7:34.)
15. Ayọ̀ ọkàn wa ti dẹ́kun; ijo wa ti yipada si ọ̀fọ̀. (Jer 25:10.)
16. Adé ṣubu kuro ni orí wa: ègbé ni fún wa, nitori awa ti ṣẹ. (Psm 89:39; Isa 3:9–11.)
17. Nitori eyi ni ọkàn wa rẹwẹsi; nitori nkan wọnyií oju wa di baibai. (Isa 1:5; Psm 6:7.)
18. Nitori oke Sioni, ti dahoro, awọn kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ nrin lori rẹ̀. (Psm 74:2,3; Neh 4:3.)

**Adura wa fun aanu.**

19. Iwọ, Oluwa, ni o wa laelae; ìtẹ́ rẹ lati ìran de ìran! (Psm 9:7; 102:12,25–27; 45:6.)
20. Eeṣe ti iwọ fi gbagbe wa laelae, ti o si kọ̀ wa silẹ ni ọjọ pipẹ? (Psm 13:1.)
21. Oluwa, yi wa pada sọdọ rẹ, awa o si yipada; sọ ọjọ wa di ọ̀tun gẹgẹ bi ti igbaani. (Jer 31:18.)
22. Ṣugbọn iwọ ti kọ̀ wá silẹ patapata, tobẹẹ ti iwọ si binu si wa gidigidi (Jer 7:29; Isa 64:9.)

26

# ESEKIẸLI

**(B.C. 595–574)**

ORI 1.

**Idájọ́ Ọlọrun lori Judah ati Jerusalemu.**

NI ọgbọn ọdún, ni oṣu kẹrin, ni ọjọ́ karun oṣu, bi mo ti wà laarin awọn ìgbèkùn leti odo Kebari, ọrun ṣí silẹ, mo sì rí iran Ọlọrun. (Esk 3:15,23; Matt 3:16; A.A. 7:56.)
2. Ni ọjọ kàrun oṣu, ti i ṣe ọdun karun igbekun Jehoiakini ọba, (2 A.Ọba 24:12.)
3. Ọrọ̀ Oluwa tọ Esekieli alufa, ọmọ Busi wá ni pataki ni ilẹ awọn ara Kaldea leti odo Kebari, ọwọ́ Oluwa sì wà ni ara rẹ̀ nibẹ. (1 A.Ọba 18:46; 2 A.Ọba 3:15.)